# IRAPADA ENIYAN

## Gẹnẹsisi 3:1-19; Ẹksodu 6:1-8; Efesu 2:1-7;

## 1 Tẹssalonika 4:13-18

## ẸKỌ 104 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Awọn ẹni-ìrapada OLUWA yio pada, nwọn o si wá si Sioni ti awọn ti orin; ayọ̀ ainipẹkun yio si wà li ori wọn" (Isaiah 51:11).**

**I Ileri Kin-in-ni ti Irapada**

1. Idanwo ejo lati mu ki eniyan ṣiyemeji aṣẹ Ọlọrun, "Õtọ li Ọlọrun wipe?" Gẹnẹsisi 3:1; Ifihan 12:9
2. Iṣubu Adamu ati Efa labẹ idanwo Satani, Gẹnẹsisi 3:2-8
3. Bi ègún ti n dé ni a si ṣe ileri irapada pẹlu; "On o fọ́ ọ li ori," Gẹnẹsisi 3:9-19; 1 Kọrinti 15:22

**II Igbala Israẹli jẹ́ Apẹẹrẹ Irapada**

4. Akanṣe ibukun Ọlọrun fun Israẹli nitori majẹmu Rẹ̀ pẹlu Abrahamu, Ẹksodu 6:1-4; Gẹnẹsisi 12:2, 3
5. Ileri Rẹ̀ lati "rà wọn pada" kuro ni oko-ẹru Egipti, Ẹksodu 6:5, 6; 12:12-14; Lefitiku 17:11
6. Ki O ba le ṣe wọn ni eniyan Rẹ, ki O si mu wọn lọ si Ilẹ Ileri, Ẹksodu 6:7, 8; 19:4-6

**III Irapada ti Awọn Ẹni Igbala ni Ayé Isisiyii**

7. Eniyan ni ipo ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ni a "sọ di ãye" lati gbé igbesi-aye titun, Efesu 2:1; 1 Kọrinti 15:45
8. Ọna ẹ̀ṣẹ ti ayé yii ti ó ti n tọ̀ ṣiwaju akoko irapada rẹ̀, Efesu 2:2, 3, 12; Orin Dafidi 1:1, 2
9. Ajinde ti ẹmí ti ẹni ti a ràpada nipasẹ Kristi, Efesu 2:4-7 Romu 6:4

**IV Iṣẹ Aṣepe Nla Nla ti Irapada**

10. Ko si ohun ti o le mu ni banujẹ bi ti aye fun awọn ti o "sùn" ninu Jesu, 1 Tẹssalonika 4:13, 14; 2 Kọrinti 7:10
11. Ajinde awọn "okú" ninu Kristi nigba ipadabọ Rẹ, 1 Tẹssalonika 4:15, 16; Jobu 19:25-27
12. Ipalarada awọn ti o wà "lãye" ninu Kristi lati pade Oluwa ni awọsanma, 1 Tessalonika 4:17, 18; Heberu 11:5; 1 Kọrinti 15:51

## ALAYE

### Eto Ọlọrun fun Irapada

Eto Ọlọrun fun irapada ki i ṣe ohun ti a ṣẹṣẹ ṣe lẹyin iṣubu eniyan. A ti pinnu rẹ̀ nipa imọtẹlẹ Ọlọrun ki a tilẹ to dá eniyan, nitori Ọdọ-agutan nì ni a "ti pa lati ipilẹṣẹ aiye" (Ifihan 13:8). Gẹrẹ ti a gegun fun aye nitori iṣubu Adamu, ni Ọlọrun, ninu ifẹ nlá nlà Rẹ fun eniyan ti o ti ṣegbe, fi eto irapada nla Rẹ hàn lẹsẹkẹsẹ bi o tilẹ jẹ pe ki i ṣe ni kikun. O sọ tẹlẹ nipa **Iru Ọmọ** ẹni ti yoo fọ́ ori Satani, Iru naa si ni Kristi, Messiah ti a ti ṣeleri. Nipa bayii ni a ri imuṣẹ Johannu 3:16 ni ibẹrẹ itan igbesi-ayé ọmọ eniyan pé, "Nitori Ọlọrun fẹ araye tobẽ̃ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni ìye ainipẹkun."

### Idande Israẹli kuro ni Egipti

Abẹli, ni titẹle ilana Ọlọrun fun idande, mu akọbi wá fun Ọlọrun ninu agbo ẹran rẹ̀. OLUWA fi oju rere wo Abẹli ati ẹbọ rẹ̀, nitori ẹjẹ ti o ta silẹ, lai si eyi ti ko si imukuro ẹ̀ṣẹ. Ni gbogbo akoko ti o ṣiwaju ikun omi ati akoko awọn patriarki, a ri awọn eniyan ti o wá Ọlọrun ti wọn si ri I, nitori gẹgẹ bi Abẹli ti ṣe, wọn mu ẹbọ wa lati inu agbo ẹran wọn. Lara wọn ni Noa, Abrahamu, Jobu, awọn wolii igba nì ati awọn miiran gbogbo ti o ri oore-ọfẹ gba lọdọ Ọlọrun nitori wọn wa idande nipa ẹjẹ naa.

Ṣugbọn idande awọn Ọmọ Israẹli kuro ninu isinru lile ni Egipti jẹ apẹẹrẹ pataki ninu eto Ọlọrun fun idande eniyan, nitori bi a ti ti ọwọ awọn akoniṣiṣẹ Egipti jẹ wọn niya, bakan naa ni ọmọ eniyan ṣe n jiya labẹ isinru Satani. "Ọ̀na awọn olurekọja ṣoro." **Irapada** ni ọrọ ti a tumọ si **igbala** ninu Majẹmu titun, eyi ni pe ki a ra ohun ti o wà labẹ akoso ẹlomiran pada, ani ki a sa kuku wi pe irapada kuro lọwọ eṣu. Ẹlẹṣẹ wà ni oko ẹru o si wà labẹ akoso eṣu. Ko si ireti idasilẹ afi bi a ba san owo irapada rẹ̀. Ko si ẹbi, ọrẹ, tabi ẹnikẹni ti o le san gbese naa. A kọ ọ pe "O si ri pe kò si ẹnikan, ẹnu si yà a pe onipẹ̀ kò si" (Isaiah 59:16). Nitori naa, Ọlọrun tikara Rẹ ran Onipẹ̀. Jesu Kristi nikan ṣoṣo ni Ẹni naa ni Ọrun ti O le san owo irapada eniyan, O si fi itẹ Rẹ̀ silẹ, O wá si aye iṣẹ́ yii lati fi Ẹjẹ Rẹ̀ iyebiye san gbese naa loke Kalfari. Ọna meji ni Agbelebu Kalfari tọka si – o tọka sẹyin si akoko ti Ofin; o si tun tọka si igba oore-ọfẹ ti o n bọ̀ wá. Gbese irapada gbogbo agbaye ni Jesu san. Oun ni o fun gbogbo eniyan ni orilẹ ati ede ni ireti. Eyi yii nikan ni ireti ti gbogbo agbaye ni lonii.

Ọlọrun, ni Ọrun gbọ́ gbigbin Israẹli; ninu aanu Rẹ nla, O si dide fun idande wọn; lọna ti Rẹ̀ ati gẹgẹ bi eto ti Rẹ̀, O mu wọn jade kuro ni oko ẹru pẹlu ọwọ lile ati ọwọ agbara. O paṣẹ fun wọn lati mu ọdọ-agutan alailabawọn kan ninu agbo ẹran wọn -- ọdọ-agutan kan fun agbo ile kọọkan ki wọn si pa a, ki wọn si gba ẹjẹ rẹ sinu awo, ki wọn si fi ewe hisopu bọ inu rẹ lati fi ẹjẹ naa wọ́n ara opo mejeeji ati atẹrigba ile wọn. O si wi pe, "Nigbati emi ba ri ẹ̀jẹ na, emi o ré nyin kọja." Ni oru ọjọ naa, igbe nla ta ni Egipti. Angẹli apanirun la ilẹ naa kọja, ilekile ti a ko si ti ri ẹjẹ, akọbi ninu ile naa ku – lati Farao ni ori itẹ rẹ titi de awọn ẹranko ninu pápá. Ṣugbọn ẹnikẹni kò kú ni Goṣeni, nitori wọn wa labẹ aabo ẹ̀jẹ nì. Ni alẹ ọjọ naa, lai si idaduro lati ọdọ awọn ọta wọn, awọn Ọmọ Israẹli kó awọn nnkan ini wọn jọ, wọn si jade kuro ni ilẹ Egipti, ọwọn ina n ṣe amọna wọn ni oru; ati ọwọn awọsanma ni ọsan, isinru lile wọn wa di ọran ìtàn!

Ẹjẹ ọdọ-agutan ti alẹ ọjọ ase irekọja tọka si Kristi. Nigba ti Ọkunrin ni de bebe odo Jordani, Johannu Baptisti kigbe wi pe, "Wò o, Ọdọ-agutan Ọlọrun, ẹniti o kó ẹ̀ṣẹ aiye lọ." Igbe ti Johannu Baptisti ke yii yẹ ki o sọ ireti jí lọkan ẹni kọọkan ti ẹru ẹṣẹ n pa. Ẹṣẹ n gbilẹ si i ninu ayé lọjọ oni, ifẹ ọpọlọpọ si n di tutu. Ṣugbọn awa naa tun le kigbe ni ohun rara bi ti Johannu pe; Wò o, Ọdọ-agutan Ọlọrun, ẹniti o kó ẹ̀ṣẹ aiye lọ." Iwọ ti o wà ni abẹ akoso eṣu sibẹ, wo Ọdọ-agutan Ọlọrun!

### Idande fun Awọn Ti A N Gbala Nisisiyii

Nigba ti awọn Ọmọ Israẹli la Okun Pupa já ni iyangbẹ ilẹ; nigba ti wọn wà ni odi keji lailewu, ti ẹgbẹ ọmọ-ogun Farao si gbiyanju lati lepa wọn, ti wọn si rì sinu ibú; nigba naa ni wọn yọ̀, o si tọ́ bẹẹ, wọn si kọrin iyin si Ọlọrun ni iranti idande nla nla wọn. Bakan naa ni ẹnikẹni ti o ba ri idande gbà ninu Kristi Jesu. "Nitorina bi ẹnikẹni ba wà ninu Kristi, o di ẹda titun: ohun atijọ ti kọja lọ; kiyesi i, nwọn si di titun."

Paulu Apọsteli ti fi ibi titun wé idande: 'Tabi ẹ kò mọ̀ pe, gbogbo wa ni a ti baptisi sinu Kristi Jesu, a ti baptisi wa sinu ikú rẹ̀? Njẹ a fi baptismu sinu ikú sin wa pọ̀ pẹlu rẹ̀: pe gẹgẹ bi a ti ji Kristi dide kuro ninu okú nipa ogo Baba, bẽni ki awa pẹlu ti o mã rìn li ọtun ìwa" (Romu 6:3, 4). Nipa bayii ẹnikẹni ti o ba ti di atunbi ti ni ajinde nipa ti ẹmi. Agbara ajinde Ọmọ Ọlọrun n ṣiṣẹ ninu rẹ̀, eyi ti o fun un lagbara lati bá Ọlọrun rìn ninu ododo ati iwa mimọ́ gẹgẹ bi Enọku igba nì. "Ẹnyin li o si ti sọ di àye, nigbati ẹnyin ti kú nitori irekọja ati ẹ̀ṣẹ nyin: ninu eyiti ẹnyin ti nrin rí gẹgẹ bi ipa ti aiye yi, gẹgẹ bi alaṣẹ agbara oju ọrun; ẹmí ti nṣiṣẹ nisisiyi ninu awọn ọmọ alaigbọran:. . . . . . Ṣugbọn Ọlọrun, ẹniti iṣe ọlọrọ̀ li ãnu, nitori ifẹ nla rẹ̀ ti o fi fẹ wa, nigbati awa tilẹ ti kú nitori irekọja wa, o sọ wa di ãye pẹlu Kristi (ore-ọfẹ li a ti fi gba nyin là). O si ti ji wa dide pẹlu rẹ̀, o si ti mu wa wa joko pẹlu rẹ̀ ninu awọn ọrun ninu Kristi Jesu" (Efesu 2:1, 2, 4-6).

Ko si si ẹni ti a gbala ti o jẹ sẹ́ eyikeyi ninu ailonka awọn eredi fun yiyọ ayọ̀ nlá nlà -- igbesi-ayé iṣẹgun, igbesi-ayé alaafia ati inu didun yatọ si igbesi-ayé okunkun ti atẹyinwa ti o dabi àla iṣọ oru. Gẹgẹ bi Paulu ti ṣe alaye rẹ, "Li akokò na ẹnyin wà laini Kristi, ẹ jẹ ajeji si anfani awọn ọlọtọ Israẹli, ati alejo si awọn majẹmu ileri nì, laini ireti, ati laini Ọlọrun li aiye" (Efesu 2:12). Iṣẹ iyipada tí ibi titun maa n ṣe tobi to bẹẹ gẹẹ ti awọn ẹlomiran fi n ro pe igbesi-ayé Onigbagbọ́ lori ilẹ ayé ni ajẹmọ anfaani idande ọkan wọn. Ṣugbọn Bibeli ni ohun miiran ju bayii lọ lati sọ fun wa nipa ilana Ọlọrun fun idande.

### Aṣepe Igbala Naa Yii

A kà á ninu Heberu 9:28 pe, "Bẽni Kristi pẹlu lẹhin ti a fi rubọ lẽkanṣoṣo lati ru ẹ̀ṣẹ ọ̀pọlọpọ; yio farahan nigbakeji **laisi ẹ̀ṣẹ** fun awọn ti nwo ọna rẹ̀ **fun igbala**." Apa kin-in-ni ẹsẹ ọrọ naa ti o wi pe, "Kristi pẹlu lẹhin ti a ti fi rubọ lẽkanṣoṣo lati ru ẹ̀ṣẹ ọ̀pọlọpọ," kò ṣoro lati yé Onigbagbọ́. A mọ pe a mu eyi ṣẹ nigba ti Kristi wá si ayé ti O si ru ẹ̀ṣẹ wa ninu ara Rẹ̀ lori agbelebu. Ṣugbọn apa keji ọrọ yii kò yé ẹlomiran: "Yio farahan nigbakeji laisi ẹ̀ṣẹ fun awọn ti nwo ọna rẹ̀ fun igbala." Awọn Onigbagbọ miiran ro pe igbala pari si iriri idalare, lai tilẹ mẹnu kan awọn iriri ti o jinlẹ ju bẹẹ lọ, isọdimimọ́ ati ifi agbara Ẹmi Mimọ́ wọni. Ṣugbọn ko si tabi-tabi ninu itumọ awọn ọrọ naa -- timọtimọ ati danindanin ni igbala wa so pọ̀ mọ́ bibọ Rẹ̀ "nigbakeji." Bi ọrọ naa si ti ṣe pataki to fara han ninu ede yii, "Fun awọn ti nwo ọna rẹ̀." Eyi rán wa leti ọrọ iyanju Jesu Oluwa pe: "Ẹniti o ba foritì i titi de opin, on na li a o gbalà" (Matteu 24:13).

Boya ẹsẹ ọrọ diẹ ati inu Episteli Peteru Aposteli yoo mu ki ẹkọ yii tubọ yé ni: "Olubukún li Ọlọrun ati Baba Jesu Kristi Oluwa wa, Ẹniti o tún wa bí, gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ̀, sinu ireti ãye nipa ajinde Jesu Kristi kuro ninu okú, sinu ogún aidibajẹ, ati ailabawọn, ati eyi ti kì iṣá, ti a ti fi pamọ́ li ọrun dè nyin, ẹnyin ti a npamọ́ nipa agbara Ọlọrun nipa igbagbọ́ **si igbala, ti a mura lati fihàn ni igba ikẹhin"** (1 Peteru 1:3-5).

### Wiwo Ọna fun Bibọ Oluwa

Ibi meji ti a ti tọka si wọnyii fihàn pe igbala wa (tabi idande) bẹrẹ lati ọjọ ti a di atunbi, o wà fun wa ni gbogbo ọjọ irin-ajo wa ni ayé yii ati titi di igba ti Oluwa yoo pada de – "bi awa ba nrìn ninu imọlẹ, bi on ti mbẹ ninu imọlẹ." A

ri i pe idande bẹrẹ pẹlu idalare o si pari si ọjọ ti a ba ṣe wa logo nigba ti Oluwa yoo sọkalẹ lati Ọrun wá lati gba Iyawo Rẹ̀ ti o ti n duro de E soke. Ọjọ yii ni Paulu Apọsteli n tọka sí ninu Episteli rẹ̀ si awọn ara Efesu pe, "Ẹ má si ṣe mu Ẹmí Mimọ́ Ọlọrun binu, ẹniti a fi ṣe èdidi nyin dè ọjọ idande" (Efesu 4:30). O si gba wa niyanju lati maa rin bẹẹ ki a si maa wọna fun bibọ Jesu to bẹẹ ki ọjọ idande yii le jẹ ireti ayọ fun ọkàn wa, nipa bẹẹ ki a le mu ki ọjọ ipadabọ Rẹ̀ dé kankan. "Nitori ore-ọfẹ Ọlọrun ti nmu igbala fun gbogbo enia wá ti farahan, o nkọ́ wa pe, ki a sẹ́ aiwa-bi-Ọlọrun ati ifẹkufẹ aiye, ki a si mã wà li airekọja, li ododo ati ni ìwa bi-Ọlọrun ni aiye isisiyi; **ki a mã wo ọna fun ireti ti o ni ibukun ati ifarahan ogo Ọlọrun wa ti o tobi, ati ti Olugbala wa Jesu Kristi"** (Titu 2:11-13). Awọn Onigbagbọ afẹnujẹ ati awọn apẹyinda kò wọna fun "ireti ti o ni ibukun" yii mọ́. Awọn ijọ ẹlẹsin ti o ti ni igbagbọ tẹlẹri ninu ipadabọ Rẹ ti pa ẹkọ yii tì nisisiyii patapata, wọn wi pe, "Nibo ni ileri wíwa rẹ gbé wà?" Wọn ti kọ Kristi Ẹni ti o wi pe, "Bi mo ba si lọ ipèse àye silẹ fun nyin, emi o tún pada wá, emi o si mu nyin lọ sọdọ emi tikarami; pe nibiti emi gbé wà, ki ẹnyin le wà nibẹ pẹlu" Lọna miiran ẹ̀wẹ, ọpọlọpọ ni o jẹwọ pe awọn gbagbọ pe Oun yoo tun pada wa ṣugbọn igbesi-aye wọn sẹ́ ijẹwọ igbagbọ wọn gidigidi. Wọn ki yoo le duro niwaju Rẹ̀ ni ọjọ naa. Ṣugbọn Jesu ní awọn eniyan kan – ani agbo kekere nì eyi ti i ṣe didun inu Baba lati fi ijọba fún. Wọn di ireti ti o ni ibukun yii mu sibẹ, wọn si dohùn pọ pẹlu Johannu Onifihan pe, "Mã bọ̀, Jesu Oluwa."

**Ori-Oke ati Afonifoji**

Ṣugbọn ẹka miiran wà ninu igbesi-ayé Onigbagbọ ninu irin-ajo rẹ̀ ni ori ilẹ ayé nipa eyi ti Ọrọ Ọlọrun gba ni niyanju, ti a ko si gbọdọ gbé oju fò dá. Onigbagbọ saba kọkọ maa n ni iriri iran ori oke ti o logo ninu eyi ti ohun gbogbo fara han ni alaafia, ayọ̀ ati inu didun. Ṣugbọn ko ni ti i rìn jinna ti yoo fi ri i pe a ni lati la afonifoji jijin kọja pẹlu. Gẹrẹ lẹyin ti Peteru Apọsteli fihan awọn Onigbagbọ nipa "ogún aidibajẹ, ati ailabawọn, ati eyi ti kì iṣá, ti a ti fi pamọ́ li ọrun dè nyin" ni o tun wi pe, "ninu eyiti ẹnyin nyọ̀ pipọ, bi o tilẹ ṣe pe nisisiyi fun igba diẹ, niwọnbi o ti yẹ, a ti fi ọ̀pọlọpọ idanwo bà nyin ninu jẹ: ki idanwò igbagbọ́ nyin ti o ni iye lori jù wura ti iṣegbe lọ, bi o tilẹ ṣe pe iná li a fi ndán a wò, ki a le ri i fun iyìn, ati ọlá, ati ninu ogo ni igba ifarahàn Jesu Kristi" (1 Peteru 1:4, 6, 7). Jesu rán awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ leti pe "Ninu aiye, ẹnyin o ni ipọnju, ṣugbọn ẹ tujuka; mo ti ṣẹgun aiye" (Johannu 16:33). Bakan naa ni Oluwa ti ẹnu Paulu Apọsteli kilọ fun ni pe, "Ọmọ mi, má ṣe alainani ibawi Oluwa, ki o má si ṣe rẹwẹsi nigbati a ba nti ọwọ́ rẹ̀ ba ọ wi: nitoripe ẹniti Oluwa fẹ, on ni ibawi, a si mã nà olukuluku ọmọ ti o gbà" (Heberu 12:5, 6). Eyi ni ọna ti Ọlọrun, ninu ọgbọn Rẹ̀, ati ninu aanu Rẹ̀ pẹlu, n gba ṣe awọn eniyan Rẹ̀ ni aṣepe fun Ijọba Ọrun naa. Apọsteli naa ni imọ ohun ti o n sọ nigba ti o kọ akọsilẹ ọrọ wọnyii, nitori o la ọpọ idanwo nla kọja, ṣugbọn o tun le fi eyi kun un pẹlu pe, "Nitori mo ṣiro rẹ̀ pe, ìya igba isisiyi kò yẹ lati fi ṣe akawe ogo ti a o fihàn ninu wa." Gẹgẹ bi oun ti ṣe, awa naa ni lati wò rekọja "ipọnju wa ti o fẹrẹ" wọnyii, ki a si tẹju mọ ileri ipadabọ Rẹ̀, si ọjọ nla ti idande. "Nitori ilu-ibilẹ wa mbẹ li ọrun: lati ibiti awa pẹlu gbé nfojusọna fun Olugbala, Jesu Kristi Oluwa: ẹniti yio sọ ara irẹlẹ wa di ọ̀tun ki o le bá ara ogo rẹ̀ mu, gẹgẹ bi iṣẹ-agbara nipasẹ eyiti on le fi tẹ ori ohun gbogbo ba fun ara rẹ̀" (Filippi 3:20, 21).

Wahala nla wà laye nisisiyii. Ẹṣẹ n di pupọ, ifẹ ọpọlọpọ si n tutu. Akoko ewu ni a wa yii. "Nitori awa mọ̀ pe gbogbo ẹda li o jumọ nkerora ti o si nrọbi pọ̀ titi di isisiyi. Kì si iṣe awọn nikan, ṣugbọn awa tikarawa pẹlu, ti o ni akọso Ẹmí, ani awa tikarawa nkerora ninu ara wa, awa nduro dè isọdọmọ, ani idande ara wa" (Romu 8:22, 23). Jesu sọ asọtẹlẹ nipa nnkan wọnyii ti n bọ̀ wá bá ayé ni igba ikẹyin, O si tun fi eyi kun un pe "Ṣugbọn nigbati nkan wọnyi ba bẹrẹ si iṣẹ, njẹ ki ẹ wò òke, ki ẹ si gbé ori nyin soke; **nitori idande nyin kù si dẹ̀dẹ"** (Luku 21:28).

## AWỌN IBEERE

1. Ka ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun naa si ori ti a le sọ pe nibẹ ni a ti ri ileri kin-in-ni nipa idande eniyan.
2. Ki ni ṣẹlẹ si ọmọ eniyan nigba naa ti a fi ni lati ṣeto irapada?
3. Njẹ ṣiwaju tabi lẹyin iṣubu eniyan ni Ọlọrun ṣeto irapada? Tọka si ẹsẹ Bibeli lati fi idi idahun rẹ mulẹ.
4. Nigba wo ni idande ẹlẹṣẹ bẹrẹ? nigba wo ni o si dé gongo?
5. Ki ni ohun pataki ti aṣepe iṣẹ irapada eniyan so pọ̀ mọ́?
6. Ki ni ireti nla pataki ti o ti n ru ifẹ ọkan Ijọ Kristi tootọ soke lati ibẹrẹ lati ba Oluwa rin pẹlu ọwọ mimọ?
7. Bi Onigbagbọ ti nla iṣoro kọja ninu ajo rẹ laye, ki ni n ṣe iranwọ lati mu un duro ninu iṣoro wọnyii?
8. Nitori ki ni Ọlọrun fi n gba iṣoro wọnyi laayè lati dé bá Onigbagbọ́?